## (99) Suratul - Salsalah

سُورَةُ الزَّلْزَلَةِ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye,*
*Aṣakẹ ọrun.*

بِسْمِ اللَّهِ الرَّحْمَٰنِ الرَّحِيمِ

**1.** Nigbati ilẹ̀ ba mi titi ni mimi rẹ̀.

إِذَا زُلْزِلَتِ الْأَرْضُ زِلْزَالَهَا ﴿١﴾

**2.** Ti ilẹ̀ yio tu ẹrù wuwo inu rẹ̀ jade.

وَأَخْرَجَتِ الْأَرْضُ أَثْقَالَهَا ﴿٢﴾

**3.** Enia yio sọpe: kiniṣe e?

وَقَالَ الْإِنسَانُ مَا لَهَا ﴿٣﴾

**4.** Ọjọ na ni (ilẹ̀) yio sọ irohin rẹ̀.

يَوْمَئِذٍ تُحَدِّثُ أَخْبَارَهَا ﴿٤﴾

**5.** Nitoripe Oluwa rẹ ti ranṣẹ si i.

بِأَنَّ رَبَّكَ أَوْحَىٰ لَهَا ﴿٥﴾

**6.** Ọjọ na awọn enia yio gba ọna ọ̀tọ̃tọ̀, ki a le fi iṣẹ wọn hàn wọn.

يَوْمَئِذٍ يَصْدُرُ النَّاسُ أَشْتَاتًا
لِّيُرَوْا أَعْمَالَهُمْ ﴿٦﴾

**7.** Nitorina ẹniti o ba ṣe iṣẹ rere bi ọmọ-inagun yio ri i.

فَمَن يَعْمَلْ مِثْقَالَ ذَرَّةٍ خَيْرًا يَرَهُ ﴿٧﴾

**8.** Atipe ẹniti o ba ṣe iṣẹ buburu bi ọmọ-inagun yio ri i.

وَمَن يَعْمَلْ مِثْقَالَ ذَرَّةٍ شَرًّا يَرَهُ ﴿٨﴾

## (100) Suratul - ’Ãdiyãti

سُورَةُ الْعَادِيَاتِ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye,*
*Aṣakẹ ọrun.*

بِسْمِ اللَّهِ الرَّحْمَٰنِ الرَّحِيمِ

**1.** Mo fi awọn ẹṣin ti nsare (lojuogun) ni mimi hẹlẹhẹlẹ (’Adiyãti) bura.

وَالْعَادِيَاتِ ضَبْحًا ﴿١﴾

**2.** Ati awọn ẹṣin ti patako ẹsẹ̀ wọn nṣana.

فَالْمُورِيَاتِ قَدْحًا ﴿٢﴾

**3.** Ati awọn ẹṣin ti nwọ inu ogun ni idaji.

فَالْمُغِيرَاتِ صُبْحًا ﴿٣﴾

**4.** Ti nwọn si nfi i tu eruku sita.

فَأَثَرْنَ بِهِۦ نَقْعًا ﴿٤﴾

**5.** Ti nwọn nbẹ si arin ijọ ogun (ni asiko ni).

فَوَسَطْنَ بِهِۦ جَمْعًا ﴿٥﴾

**6.** Dajudaju enia jẹ alaimore si Oluwa rẹ̀.

إِنَّ ٱلْإِنسَٰنَ لِرَبِّهِۦ لَكَنُودٌ ﴿٦﴾

**7.** Atipe dajudaju lori eyi on jẹ ẹlẹri si i.

وَإِنَّهُۥ عَلَىٰ ذَٰلِكَ لَشَهِيدٌ ﴿٧﴾

**8.** Atipe o jẹ ẹniti o wà ifẹ ohun rere maiya.

وَإِنَّهُۥ لِحُبِّ ٱلْخَيْرِ لَشَدِيدٌ ﴿٨﴾

**9.** Abi on kò mọ̀ ni pe nigbati a ba tu jade ohun ti o mbẹ ninu awọn sãre.

۞ أَفَلَا يَعْلَمُ إِذَا بُعْثِرَ مَا فِى ٱلْقُبُورِ ﴿٩﴾

**10.** Ti a si ṣe afihan ohun ti mbẹ ninu igbaiya.

وَحُصِّلَ مَا فِى ٱلصُّدُورِ ﴿١٠﴾

**11.** Dajudaju Oluwa wọn mọ̀ nipa wọn (pãpà) ni ọjọ na.

إِنَّ رَبَّهُم بِهِمْ يَوْمَئِذٍ لَّخَبِيرٌۢ ﴿١١﴾

## ***(101) Suratul - Kọri'ah***

## سُورَةُ ٱلْقَارِعَةِ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye, Aṣakẹ ọrun.*

بِسْمِ ٱللَّهِ ٱلرَّحْمَٰنِ ٱلرَّحِيمِ

**1.** Ẹrù a kan-ni ni àiyà (Kõri'ah).

ٱلْقَارِعَةُ ﴿١﴾

**2.** Kini akan ni ni aiya (ẹ̀rù) nã jẹ?

مَا ٱلْقَارِعَةُ ﴿٢﴾

**3.** Kini o fi (ẹrù) akan ni ni aiya nã mọ ọ?

وَمَآ أَدْرَىٰكَ مَا ٱلْقَارِعَةُ ﴿٣﴾

**4.** (On ni) ọjọ ti awọn enia yio dà gẹgẹbi afopina ti o tuka kiri.

يَوْمَ يَكُونُ ٱلنَّاسُ كَٱلْفَرَاشِ ٱلْمَبْثُوثِ ﴿٤﴾